# Àkíyèsí Àwọn Ẹ̀tọ́ Òṣìṣẹ́
# Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti ÀÀBÒ tí a Kò Lò:

O ní ẹ̀tọ́ sí ìgbà ìsinmi ààbò àti àìsàn àti ìgbà ìsinmi ṣáájú ìbímọ tí a sanwó fún. O ni ẹtọ yi ipòkipò yòówù kí ipò isilọ-si-ilu-mìí rẹ jẹ́. Agbanisiṣẹ rẹ gbọdọ fún ọ ní akiyesi yi to nsàlàyé awọn ẹtọ rẹ.

## Iye Ìgbà ìsinmi:

| **Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti ÀÀBÒ tí a Kò Lò**<br>(bìkítà fún ara rẹ tàbí ẹnikẹ́ni tí o kà sí ẹbí rẹ) | **Ìgbà ìsinmi Ṣáájú ìbímọ Tí a sanwó fún**<br>(ìtọ́jú ìlera fún ara rẹ lásìkò oyún níní) |
|---|---|
| • Gbogbo àwọn agbanisíṣẹ́ gbọdọ̀ pèsè iye tí ó tó **wákàtí 40 ti ìgbà ìsinmi ààbò àti àìsàn** ní ọdún kọ̀ọ̀kan.<br>• Àwọn agbanisíṣẹ́ tí ó ní àwọn òṣìṣẹ́ 100 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ gbọ́dọ̀ pèsè ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí ó tó **wákàtí 56 ní ọdún kọ̀ọ̀kan**.<br>*Àwọn òṣìṣẹ́ alákòókò kíkún àti àwọn alákòókò díẹ̀ ń gba ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo ní òṣùwọ̀n wákàtí* ***1 fún gbogbo wákàtí 30 tí wọ́n fi ṣiṣẹ́.*** | • Gbogbo àwọn agbanisíṣẹ́ ní láti pèsè báńkì tó yàtọ̀ ti **wákàtí 20 ìgbà ìsinmi tí a sanwó fún ṣáájú ìbímọ.** |

Ọdún kàlẹ́ndà ti agbanisíṣẹ́ rẹ ______________________ jẹ́:_______________________
Oṣù Kini Oṣù tó kẹhin

O ní ẹ̀tọ́ láti bọ́ lọ́wọ́ ẹ̀san lati ọwọ́ agbanisíṣẹ́ rẹ fún lílo ìgbà ìsinmi àìsàn ati aabo TI A SANWO FUN.

- Agbanisiṣẹ rẹ ni awọn oṣiṣẹ márùún tabi jubẹlọ.
- Agbanisíṣẹ́ rẹ kò ní to àwọn òṣìṣẹ́ 5 ṣùgbọ́n owó tí ó nwọlé léyìn owó orí ti mílíọ̀nù $1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- O ń ṣiṣẹ́ nínú ilé ẹnìkan gẹ́gẹ́ bíi òṣìṣẹ́ abẹlé; fún àpẹrẹ olùtọ́jú ọmọ, olùtọ́jú ilé, tàbí òṣìṣẹ́ amúgbálẹ́gbẹ.
  *Àkíyèsí:* Òfin náà dáàbòbo oṣiṣẹ abẹle kan tàbi jubẹlọ nínú ilé kan.

O ní ẹ̀tọ́ láti bọ́ lọ́wọ́ ẹ̀san lati ọwọ́ agbanisíṣẹ́ rẹ fún lílo ìgbà ìsinmi àìsàn ati aabo TI A SANWO FUN.

- Agbanisiṣẹ rẹ ni awọn oṣiṣẹ ti o din márùún ti akopọ owó tó nwọle din ni mílíọ̀nù kan dọlà.

Èyítí ó tó wákàtí ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí a kò lò ni o le sún sí ọdún tí ń bọ̀.

## Iye Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti Ààbò:

- Lò ó fún ìlera rẹ, ati lati gba ìtọ́jú isegun tàbi fún ìwòsàn kúrò nínú àìsàn tabi ifarapa.
- Lò ó láti ṣètọ́jú mọ̀lẹ́bí kan tó ń ṣàìsàn tàbí tó ní láti lọ sílé ìwòsàn.
- Lò ó nigbati iṣẹ rẹ tàbí ilé ìwé ọmọ rẹ bá tilẹkun pàjáwiri nitori ìlera ará ìlú.
- Lò ó fún ààbò rẹ tabi ààbò mọlẹbi kan nitori iwa-ipá abẹle, ifọwọpanilara ti ó kò fẹ́ fún ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tabi ifipá tani sókè òkun.

Agbanisíṣẹ́ rẹ lè ní kí o ṣe ìfitónilétí ṣáájú ìgbèrò lílo ìgbà ìsinmi; fún àpẹẹrẹ, láti lọ rí dókítà tàbí lọ sí ibi ìgbéjọ́ tí a ti ṣètò. O kò ní láti ṣe ìfitónilétí ṣáájú ní ti lilo ìgbà ìsinmi láìròtẹ́lẹ̀; fún àpeẹrẹ, àìsàn tàbí ìṣègùn pàjáwìrì.

O ní ẹ̀tọ́ láti sọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ. O kò ní láti sàlàyé lẹkunrẹrẹ fún agbanisíṣẹ́ rẹ ìdí tí o fi lo ìgbà ìsinmi.

Agbanisíṣẹ́ rẹ lè nílò ìwé àkọsílẹ̀ tí o bá lò ju ọjọ́ iṣẹ́ méta ti ìgbà ìsinmi lọ nígbà kan náà.

## Àwọn Ìfihanni Tí A Kọ Sílẹ̀ Tí A Béèrè Fún:

Agbanisiṣẹ rẹ gbọdọ:

- Fún ọ ní àkọsílẹ̀ ilana tó nsàlàyé bí o ṣe lè lo àwọn àǹfààní rẹ.
- Sọ fún ọ iye ìgbà ìsinmi tí o ti lo àti èyí tí ó kù ní àkókò ìsanwó kọ̀ọ̀kan.

## Kò sí Ìgbẹ̀san:

Ó lòdì sí òfin láti fiyà jẹ tàbi sèdádúró lénu iṣẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ nítorí pé wọ́n bèrè fún tàbí wọ́n ń lo ìgbà ìsinmi tàbí fún jíjábọ̀ titàpá sí òfin.

NYC Consumer and Worker Protection

**Kàn si Ìdáàbòbò Olùrajà ati Oṣiṣẹ lati kọ́ sì tabi lati kọ'we ẹ̀sùn.**
Lọ sí **nyc.gov/workers** | Pè **311** kí o sì bèèrè fún “Ìgbà ìsinmi Àìsàn àti Ààbò Tí a sanwó fún”
O si tún lè ṣe ìtanilólobó ÀÌLÓRÚKỌ.

05/30/2025